# AJỌ AGỌ

## Lefitiku 23:33-44; Deuteronomi 16:13-17

## ẸKỌ 88 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Gbogbo ẹ̀bun rere ati gbogbo ẹ̀bun pipé lati oke li o ti wá, o si nsọkalẹ lati ọdọ Baba imọlẹ wá" (Jakọbu 1:17).**

**Ajọ Ikẹyin**

Ajọ kẹta ati eyi ti o kẹyin ti Ọlọrun n fẹ ki awọn Ọmọ Israẹli pamọ ni a n pè ni Ajọ Agọ, tabi Ajọ Ikore Oko. Lati ọjọ kẹẹdogun oṣu keje ti awọn Ju, gbogbo ọkunrin yoo fi ara wọn hàn niwaju Ọlọrun lẹẹkan si i. A ti kọ́ ẹkọ nipa ajọ ọsẹ eyi ti wọn maa n ṣe ni akoko ikore ọkà. Lẹyin ti a ba ti kore gbogbo irugbin tán patapata, ti a ba si ti kó gbogbo eso ilẹ̀ naa jọ, wọn yoo tun pade fun ajọ ikore oko. Eyi jẹ iranti igba ti awọn Ọmọ Israẹli n gbé ninu agọ ni akoko irin-ajo wọn ninu aginju, ati ti ikore (tabi ikojọ) ohun ọgbin wọn ni ọdun naa.

Ajọ ikore oko jẹ́ ọkàn ninu awọn ajọ mẹta ti Ọlọrun ti pa laṣẹ fun awọn Ọmọ Israẹli lati maa ranti nigbakuugba. Ni akoko yii wọn a pejọ pọ̀ pẹlu ọrẹ ati iyin si Ọlọrun, ki i ṣe fun ohun ti O ti ṣe fun wọn lati ẹyin wá nikan, ṣugbọn fun ibukun ti wọn ri gbà ni akoko ikore kọọkan nigba ti wọn ba kó ohun ọgbin wọn pamọ fun akoko ti o n bọ̀. A ko gbọdọ kuna lati maa dupẹ ati lati maa yin Ọlọrun logo fun ohun ti O ti ṣe fun wa. Fun ibukun ti o kọja ati eyi ti a n ri gba lọwọlọwọ, a ni lati maa fi ara wa rubọ lojoojumọ fun Oluwa.

Ipejọpọ fun ajọ yii dabi igba ti awọn eniyan ba lọ si ile-isin lonii fun ipade. Kiki pe ipejọpọ yii wa fun odindi ọsẹ kan gbako, o dabi ipejọpọ fun ajọ agọ ti wa. A fun wọn ni ofin ti o yé wọn daradara, gẹgẹ bi wọn ṣe ni lati sin Ọlọrun ni akoko ajọ naa. Ọjọ kin-in-ni ati ọjọ kẹjọ yoo jẹ́ ọjọ mimọ́; wọn kò gbọdọ ṣe iṣẹkiṣẹ kan, wọn ni lati pa ọjọ wọnyii mọ́ gẹgẹ bi Ọjọ Isinmi. Lọjọ kọọkan ni wọn yoo maa ṣe irubọ pataki si Oluwa. Ninu Numeri ori kọkandinlọgbọn (29), a kà nipa awọn ẹran ti wọn yoo lò – ọdọ-agutan, ọmọ ewurẹ, àgbò ati maluu – ati iye ti wọn ni lati fi rubọ lọjọ kọọkan jalẹ ọsẹ naa. Nigba ti a ba lọ si ile-isin ati nigbakuugba ti a ba fi ara wa fun Ọlọrun, a kò beere lọwọ wa lati mu ẹbọ ẹran wá. Oluwa n fẹ ki a fun Oun ni ẹbọ iyin. Awọn ọmọ Ọlọrun maa n yin In ninu orin, ninu adura, ninu ẹri, nipa bi wọn ti n fi eti silẹ si iwaasu ati bi wọn ti n huwa ninu ile-isin pẹlu.

**Idupẹ**

Orilẹ-ede Amẹrika, pẹlu ti ya ọjọ kan pataki sọtọ ninu ọdun fun idupẹ. A n pè é ni Ọjọ Idupẹ, eyi ti wọn bẹrẹ ni ọdun pupọ sẹyin, lati maa dupẹ lọwọ Ọlọrun fun ounjẹ ti awọn eniyan kó jọ. A ti maa n sọ nigba pupọ pe ojoojumọ ni ọjọ idupẹ fun Onigbagbọ. A kò fẹ jẹbi fifi ọpẹ fun Ọlọrun ni ọjọ kan laaarin ọdun, tabi ni ọjọ kan laaarin ọsẹ kan.

Ninu ori kẹta Iwe Oniwasu, a kà pe akoko wà fun ohun gbogbo – akoko irugbin, akoko lati kore ohun ti a gbin, akoko ẹkun ati ẹrin. Ajọ agọ jẹ akoko yinyin Ọlọrun logo ati riru ẹbọ. Nigba ti a ba wá si ile Ọlọrun tabi igbakuugba ti a ba wà niwaju Ọlọrun a gbọdọ ranti pe akoko ọ̀wọ̀ ni, akoko mimọ́, akoko fun iyin Ọlọrun. A o wá tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀, a o si ṣe isin wa letoleto. A n fẹ lọ sọdọ Ọlọrun pẹlu imurasilẹ lati ṣe ẹbọ iyin ati ifararubọ.

Ni akoko awọn ajọ wọnyii, wọn yoo mu ọrẹ ẹbọ wá **pẹlu** ẹbun, **pẹlu** gbogbo ẹ̀jẹ́ wọn, **pẹlu** gbogbo ẹbọ atinuwa wọn (Lefitiku 23:37, 38). "Ki olukuluku ki o mú ọrẹ wá bi agbara rẹ̀ ti to, gẹgẹ bi ibukún OLUWA Ọlọrun rẹ ti o fi fun ọ" (Deuteronomi 16:17). Awọn miiran rò pe awọn ṣe ohun nla kan, nigba ti wọn ba ṣe ohun ti wọn ni lati ṣe. Ṣugbọn Ọlọrun n fẹ ki a ṣe ju bẹẹ lọ. Awọn Ọmọ Israẹli ni lati rú awọn ẹbọ pataki kan, ṣugbọn Ọlọrun n beere ẹbun ati ọrẹ-atinuwa wọn. Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin ninu Luku 17:10 pe, "Nigbati ẹ ba ti ṣe ohun gbogbo ti a palaṣẹ fun nyin tan, ẹ wipe, Alailere ọmọ-ọdọ ni wa."

**Yiyọ Ayọ̀**

Awọn eniyan wọnyii yọ̀, inu wọn si dùn fun ibukun ti ara ti Ọlọrun fun wọn eyi ni ohun ọgbin wọn. Wọn si gbẹkẹle Ọlọrun fun eso ilẹ wọn ni ọjọ iwaju. Dajudaju, wọn boju wo ẹyin wo akoko ti wọn kò ní oko ti wọn yoo ro, ti wọn ko si ni ohun ọgbin ti wọn yoo kore. Awa naa, pẹlu gbọdọ maa yin Ọlọrun logo nigba ti a ba ka awọn ibukun wa nipa ti ara ati nipa ti ẹmi. A le wo ẹyin ki a si ranti akoko igba ti ojurere Ọlọrun kò si ni igbesi-ayé wa nitori ẹ̀ṣẹ.

Awọn Ọmọ Israẹli ni lati "Ma yọ̀ niwaju OLUWA, "a si ka ohun kan naa ni ibi pupọ ninu Majẹmu Titun. A kà pe "Awa si nṣogo ninu Kristi Jesu" (Filippi 3:3); "Ẹ mã yọ̀ ninu Oluwa nigbagbogbo" (Filippi 4:4); Ẹ mã yọ̀ nigbagbogbo" (1 Tẹsalonika 5:16); Ṣugbọn ẹ kuku yọ̀, pe, a kọwe orukọ nyin li ọrun" (Luku 10:20). Onigbagbọ kò gbọdọ banujẹ rara. Onigbagbọ maa n yọ̀ nigba aisan paapaa ati nigba ti nnkan ba ṣoro fun un. Awọn ọmọ-ẹyin yọ̀ pe a kà wọ́n yẹ lati jiya fun orukọ Jesu. Awa pẹlu n yọ̀ ni ireti pe a o wà ninu ikore ikẹyin – nigba ti a o kó awọn ayanfẹ lọ si ile.

Awọn miiran maa n yin Ọlọrun, ṣugbọn inu wọn ki i dun, bẹẹ ni oju wọn ki i fi ayọ̀ hàn. "Ẹ hó iho ayọ si Ọlọrun" (Orin Dafidi 66:1). A fẹ ṣe ju pe ki a gbohùn wa soke si Ọlọrun: a fẹ ṣe e pẹlu ayọ̀ ati inu didùn.

**Lati Gbé Inu Agọ**

Ni akoko ajọ agọ́, awọn Ọmọ Israẹli ni lati maa gbé ninu agọ́ ti a fi ẹka igi ṣe. Wọn a maa lo ẹka igi, -- imọ ọpẹ ati igi wilo pẹlu.

Wọn fi ile wọn silẹ wọn si n gbé, fun ọjọ meje, ninu agọ wọnyii ti a fi ẹka igi kọ́. Eyi ni lati rán wọn leti agọ ti wọn n gbé inu rẹ̀ ni akoko irin-ajo wọn ninu aginju. Wọn kò ni ile ti o dara nibẹ, ṣugbọn Ọlọrun tikara Rẹ̀ fi awọsanma ṣiji bò wọn. O si tun n fi ṣe amọna wọn (Orin Dafidi 105:39). Lẹyin igba ti wọn ti gbé ninu agọ wọnyii fun ọsẹ kan, wọn dupẹ fun itura ti wọn ni ninu ile wọn. Nigba miiran o dara fun wa lati ranti bi a ti n gbé ninu agọ iwa buburu tẹlẹ ri, nigba naa ni a o mọ riri ibukun ti a ni nipa gbigbé ninu Oluwa. A o si mọ riri aabo, itunu ati anfaani ti o wà ninu Ihinrere.

Awọn miiran gbadun ile wọn ninu ayé yii to bẹẹ ti wọn kò le fi wọn silẹ lati sin Oluwa. A fẹ dabi Paulu nigba ti o n kọwe si awọn ara Heberu, "Nitoripe awa kò ni ilu ti o wà titi nihin, ṣugbọn awa nwá eyiti mbọ̀." Ilu ti o n sọ nipa rẹ̀ ni Ọrun, Ilu ni eyi ti Ọlọrun kọ́, ti O si jẹ́ Alakoso rẹ̀. A n fẹ lati maa rò nipa ile daradara ti Jesu ti lọ pese silẹ fun wa. A fẹ wa ni imurasilẹ ki a ri igbala, ki a si mura silẹ fun ikore nlá nlà nì, ti yoo ṣẹlẹ lai pẹ nigba ti a o kó awọn eniyan Ọlọrun jọ.

**Ọrọ Mose**

Mose jẹ olooótọ lati kọ́ awọn Ọmọ Israẹli nipa awọn ajọ wọnyii, nitori wọn jẹ Ofin ti wọn gbọdọ pamọ́. Ki i ṣe gbogbo aṣaaju awọn Ọmọ Israẹli ni wọn jẹ olooótọ si wọn, fun ọdun pupọ ni wọn kò fi pa ajọ agọ yii mọ́. A kà ninu Nehemiah ori kẹjọ (8) nipa akoko kan ti a mu Ofin yii wá si iranti wọn. Ni akoko Nehemiah ati Esra, wọn ka Iwe Ofin yii fun awọn eniyan, wọn si kọ́ nipa ajọ yii ti o n bẹrẹ ni ọjọ kẹedogun oṣu keje, eyi ni ajọ agọ.

Awọn Ọmọ Israẹli fi ẹka igi pa agọ, wọn si n gbé inu wọn, gẹgẹ bi a ti paṣẹ fun wọn lati ṣe. "Ayọ nlanla si wà" (Nehemiah 8:17). Ayọ nlá nlà ni a maa n ní nigba ti a ba gbọran ti a ba si ṣe ohun ti Ọlọrun n fẹ ki a ṣe.

Bawo ni ọkàn wa ti kun fun ọpẹ to lonii nitori awọn alufaa ti wọn n kọ́ wa ni gbogbo ẹkọ Bibeli. Wọn jẹ́ olooótọ si sisọ fun wa, ki i ṣe kiki ohun ti Ọlọrun n beere lọwọ wa ati ọrẹ atinuwa, irubọ igbesi-ayé wa, akoko wa, ati ẹbun (talẹnti) ti a ni, gbogbo iwọnyi ti Ọlọrun n fẹ nikan, ṣugbọn wọn n sọ fun wa pẹlu nipa awọn anfaani ti a ni ati awọn ileri ti o jẹ ti wa. Ẹ jẹ ki a jẹ ọ̀kan ninu awọn wọnni ti wọn ni ibukun Ọlọrun ni igbesi-ayé wọn nipa igbọran. Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe, "Bi ẹnyin ba mọ̀ nkan wọnyi, alabukun-fun ni nyin bi ẹnyin ba nṣe wọn" (Johannu 13:17).

**AWỌN IBEERE**

1. Ajọ wo ni o kàn lẹyin akoko ikore ọkà?
2. Ajọ wo ni wọn maa n ṣe lẹyin ipari gbogbo ikore?
3. Sọ orukọ miiran ti a n pe ajọ agọ́.
4. Ki ni ṣe ti eyi jẹ́ akoko ayọ̀?
5. Akoko miiran wo ni a lo imọ-ọpẹ nigba ti awọn eniyan n yin Oluwa?
6. Ki ni ṣe ti wọn n gbé inu agọ?
7. Ikore nlá nlà wo ni o ṣi n bọ̀ wá ṣẹlẹ̀?